## Ipo Ti Awon Ohun Ogbin Imo-Ero Ti O Ye Fun Tita Wa Lagbaye: Ti Odun 2014

**Onkowe Ni Clive James, Ti O je Oludasile Ati Alaga Ana Ti Ajo ISAAA**

**A ko eyi lati saami ayeye ojo ibi oloogbe Norman Borlaug ti o pe ogoorun odun ni *(25th of March 2014)*, eni ti o gba ami eye Nobel Peace Laureate, ti o si je oluldasile ISAAA**

---

### KOKO MEWAA TI O GA JULO nipa eto ogbin imo-ero(Biotech\GM) ni odun 2014

**KOKO KINI. 2014 je odun kokan-dinlogun aseyori okoowo eto ogbin imo-ero biotech.** Lati igba akoko ti a ti s'ogbin yii ni odun 1996, saare oko ti a nlo ti gbe peeli sin ni ona ti o wuyare, eyi to din igba kan milionu ni bilionu meji(*1.8billion hectares*) saare(ti o ju billion merin abudare) ti a fi sogbin, iwon agbegbe bii ida ogoorin ninu ogoorun*(80%)* ti o ju ile **China** tabi **United States** lo. Orileede meji-din-logbon*(28)* lo sogbin imo-ero biotech ni odun 2014, ni eyi ti o mu ki saare oko ohun peleke sii ni ilopo ogoorun *(100-folds)*lati milionu kan abo-lerugba ni odun 1996 si okan-le-logoosan milionu saare le-leedegbeta ni 2014- eyi to tumosi milionu mefa-le-oodunrun saare*(1.7 million)* ti o fi ju milionu marun-un(*5.0million)* ti 2013 ni igbe-peeli ti odoodun ni nkan bii ida meta tabi merin ninu ogoorun*(3-4%)*. Igbepeeli onilopo ogoorun yii lo mu ki ona eto imo ogbin Bt di itewogba laipe yii - kini idire –won ni ere to po jojo. Iye awon orileede to sogbin imo-ero biotech fi ilopo merin ju mefa ti odun 1996 to fi di meji-dinlogbon ni 2014, ilekan sii ju ti 2013 lo.

**KOKO KEJI. Iye awon agbe to n sogbin imo-ero biotech.** Milionu meji-dinlogun *(18million)*awon agbe leyi ti ida aadorun ninu ogoorun*(90%)* ninu won je oloko kekere ati akuuse, ni akosile fihan pe won sogbin saare okan-le-logoosan milionu(*181million hectares*) nilana imo ero **biotech** lorileede meji-dinlogun ni odun 2014. Awon agbe lo mo bi a se nsagbefo ewu ati bi a se nte siwaju ninu kikore nipa hiho koko mo ona ti a fi n sagbe yii(eleyi to fi oko dida si bilionu kan abo saare fun ogbin sise ti o si ndaabo bo awon aginju ati awon ohun abemi to wa layika). Milionu meje-o-le-ogoorun*(7.1million)*agbe kereje ni orileede **China** ati milionu meje-le- eedegberin*(7.7million*) ni India lo dibo yan lati gbin owu Bt sori saare oko to ju milionu meedogun (*15million*)lo ni 2014, nitori ere ti o joju ti won nri nibe. Bakanaa ni odun 2014 ti a n wi yii, o to bii irinwo-le-meedogun lona egberun 415,000 awon agbe kereje to janfaani agbado/oka Bt ni orileede **Philippines**.

**KOKO KETA. Ipinu oselu to muna-doko ni yoo mu ki orileede Bangladesh maa ta igba Bt (brinjal) fun igba akoko.** Bangladesh, orileede kekere ti o tun kuuse pelu ogoorun kan abo milionu *(150million*)awon olugbe ibe lotewogba iye ti a nta igba Bt(brinjal) ni 30/10/2013 -o tun wa lakosile pe – laarin osu meta ati bii ojo mewa ti won se itewogba yii – awon agbe kereje sogbin igba brinjal Bt ni 22/01/2014. Irufe aseyori yii kiba mati seese ti ko ba je wipe ijoba satileyin fun won, paapajulo Minisita fun eto ogbin Matia Chowdhury – iru apeere ti o ye ki awon orileede kekeeke maa sawokose re. Orileede **Bangladesh** je ibi ti a ti n dan awon ohun ogbin bii anamo, iresi ati owu Bt wo ni gbigbin.

**KOKO KERIN. Irufe awon ohun ogbin ti imo-ero 'tuntun' ti o sese je itewogba fun gbigbin awon ounje ti maa saaba je bii anamo ni orileede US ati igba(brinjal) ni Bangladesh.** Ni odun 2014, orileede **US** bowolu lati maa sogbin awon ohun 'tuntun' meji bii: anamo ibile, ti o je ounje ti a maa nje deede ti ko ni eroja (acrylamide) to po, leyi to le sokunfa arun edo fooro ati pe kii sofo pupo nitoripe kii saaba loju ogbe lara; ati pelu ewebe(alfalfa) ti ko ni 'lignin' pupo bi iru KK179(HarvXtra) ti o maa n da kiakia ti a ba je pelu isedeede re ti a ba gbin-in(alfalfa je nomba 1irufe koriko ti awon eranko maa nje lagbaye). Orileede **Indonesia** tewogba ireke ti eerun kii baje. **Brazil** bakanaa tewogba ohun ogbin **Cultivance**, ewa soya ti HT, ewa to maa ndena kokoro arun, ti a gbin labele pelu imo-ero biotech ni o ti wa fun gbigbin ni odun 2016. **Vietnam** fountelu agbado Bt(HT and IR) fun igba akoko ni odun 2014. Pelu awon ohun ogbin imo-ero biotech ti a nj'anfaani won lowolowo bii: Agbado funfun ni South Africa, ohun ogbin ti a fii se suga ati oka oloyin ni **US** ati **Canada**, ibepe ati eeri ko si gbeyin. Awon ohun ogbin imo-ero **biotech** tuntun ti gori igba bii: ayaaba ninu awon ewebe(igba brinjal) ni **Bangladesh** ati anamo ni **US** – anamo yii kanaa ni ekerin ninu awon ounje ti a maa nje ju lagbaye ti o si nmu ki ounje po yanturu lorileede **China**(million mefa saare oko anamo), **India**(million meji) ati **EU** ti o je bii million meji.

**KOKO KARUN-UN. Awon orileede marun ti o leke nipa sisogbin awon ohun ogbin imo-ero biotech.** Orileede US l'o si n gbegba oroke pelu aadorin-o-le-meta ati ogoorun million saare oko*73.1million*(ida ogooji ninu ogoorun lagbaye) pelu iye to ju ida aadorun ninu ogoorun agbado ti o je itewogba(ida aadorun-le meta ninu ogoorun itewogba), ewa soya je ida merin-le laadorun ninu ogoorun ti ti owu je ida merin-dinlogoorun ninu ogoorun(96%). Orileede **Brazil** lo se ipo kini, l'odun marun leralera, US se ipo kini bakanaa ni odun 2014, pelu milionu meta saare, ni afiwe pelu millionu meji din ogoorun saare ti o je ti orileede Brazil. Patakijulo, orileede **Brazil** yii kanna tun sogbin ewa soya HT/IR ti o ni akosile ti o to millionu marun-un –o-le igba saare lodun keji leyin ti a se ifilole ewa ohun. Orileede **Argentina** si wa nipo keta ti o wa teleri ni ipada seyin ranpe pelu milionu merin-le-logun-o-le oodurun saare lati milionu merin-le-logun-o-le irinwo( ti o wa ni odun 2013. **India** ti o wa ni ipo kerin l'akosile fihan pe O sogbin owu Bt sori saare oko to to milionu mokanla-o-le-egbeta*(11.6)(*ti 2013 je milionu mokanla geere) pelu itewogba ida marun-din-logoorun ninu ogoorun. **Canada** ti o wa ni ipo karun-un lo sogbin (*24.4million)*imo-ero biotech sori milionu mokanla-o-le egbeta saare pelu opolopo **Canola** ati atewogba ti o je ida merin-din-

logoorun ninu ogoorun pelu adinku ogbin **Canola**. Ni odun 2014, okookan awon orileede marun-un t'o leke lo sogbin to ju milionu mewa saare, eyi t'o npese aye to gbooro ati ipile rere fun ogbin ojo ola.

**KOKO KEFA. orileede US ni a ti koko sisogbin Agbado ti eerun kii baje ni odun 2013 ti o si gbe peeli si ni ilopo marun-un ni odun 2014.** Agbado ti eerun kii baje ti o si ni edidi eerun ti biotech lara yii ni a koko sogbin re ni orileede US ni odun 2013, ti o si gbe peeli ni ilopo marun abo lati egberun lona aadota saare l'odun 2013 si egberun lona igba-o-le arundinlogoorin ni odun 2014 ti o n sapeere bi awon agbe se tewogbasi – irufe eyii kanaa lo sele si ibasepo\idokowo to wa laarin awon araalu ati aladani, Agbado ti ko nilo omi pupo for Afrika ti a npe ni(WEMA) leyii ti yoo mu ki agbado ti eerun kii baje ti biotech di pinpin fun awon orileede ti a sayan nile Adulawo ni odun 2017.

**KOKO KEJE. Ipo ti awon ohun ogbin imo-ero biotech wa ni ile Adulawo(Africa).** Afirika si n tesiwaju pelu orileede Gusu Afirika(South Africa), ti o dinku ni iwon milionu meji- o-le eedegberin saare ti oda baje. **Sudan** gbe peeli si ni gbingbin owu Bt ni ida aadota ninu ogoorun ti eerun sokunfa igbepeeli saare ti o to eedegbeta ti **Burkina Faso** fi sogbin. Awon orileede meje miran bii:(Cameroon, Egypt, Ghana, Kenya, Malawi, Nigeria ati Uganda) ni won lo si papa lati mo awon ohun ogbin t'o le ya eyi to dara soto laarin awon to le saidara, igbese ti o keyin si fifontelu awon ohun igbin naa. Patakijulo, ise ti WEMA nse l'o sagbekale agbado ti eerun tabi kokoro ko le baje, akoko iru re, ti a gbin ni ona imo-ero biotech fun orileede South Afrika fun odun 2017. Aini isakoso ti o niise pelu imojinle Sayensi, to gun rege ti ko nani lowo tabi gba akoko eni yoo maa je idena fun itewogba ilana eto ogbin yii. Isakoso to wuyi, ti a fi taratara se sugbon ti ko mu iyonu lowo ni awon agbe kereje ati orileede kekeeke, ti osi nta, ti o sese ngoke agba nilo.

**KOKO KEJO. Ipo ti awon ohun ogbin imo-ero biotech wa ni EU.** Orileede EU marun-un ntesiwaju lati maa sogbin agabdo biotech sori saare oko ti o to egberun lona meta-le lelogooje eyi t'o dinku pelu ida meta ninu ogoorun ni odun 2013. Orileede **Spain** nleke ajo EU pelu saare bii okan-le-laadoje egberun ti won fi sogbin agbado Bt, ti o dinku ni ida meta ninu ogoorun si ti odun 2013, ti o si je wipe nipa akosile ida mokanlelogbon ninu ogoorun tewogba ni odun 2013 ohun. Ni kukuru, awon orileede meta lo ti gbe peeli sii ti awon meji si faseyin die, latari pe won ko gbiin agabdo doju amin ati pe won ko polongo re.

**KOKO KESAN. Awon anfaani ti o ro mo awon ohun ogbin imo-ero biotech.** Agbekalee ayewo finifini tuntun lagbaye ni 2014 safihan ilopo anfaani to ro mo awon ohun ogbin wonyii lati nkan bii ogun odun si asiko t'awa yii. Ayewo finifini lagbaye ti a se pelu iwadii lona metadin laadoje lati bii ogun odun si asiko yii, fidi re mule pe itewogba imo-ero GM ti dinwo oogun apakokoro ku nipa lilo ida meta din logooji ninu ogoorun, eyii mu ki ire oko po sii ni ida mejilelogun ninu ogoorun nigbati ere awon agbe po sii ni iwon ida meji-din laadorin ninu ogoorun. Iwadii wonyii fidi awon esi ti a maa nri lodoodun ninu awon iwadii agbaye miran mule. Akosile ti a ni laarin odun 1996 si 2013, fihan pe awon ohun ogbin imo-ero biotech mu ki ounje po ya-n-turu, o si tun mu ki oju ojo ati ayika duro deede nipa: mimu ki ohun ogbin po si ni iye owo to to billionu meta-le laadofa Dola(US$133billion), o si nseto ayika to dara nipa didin ilo oogun apa kokoro ku ni iwon bii eedegbeta kilo(500kg): ni odun1996 si 2012; ni odun 2013 nikan o din afefe oloro CO2 ku ni iwon billionu meji din-logbon kilo ti o dogba pelu kiko millionu mejila-o-le irinwo moto kuro loju popo fun odun kan; didaabo bo awon ohun abemi ti o wa layika pelu ididaabo bo saare ile to to millionu meta-le –laadofa ni odun 1996 si 2013; ati didin osi ku laarin awon agbe kereje ti o ju millionu merindinlogun abo ati awon ebi won to ju millionu marun -dinlaadorun, eyi ti won wa lara awon eniyan to tosi ju lagbaye. Eto ogbin imo-ero yii se Pataki ni tooto, sugbon kii se ona abayo ati titeramo sise agbe lona ti o dara bii akore-dare-si ati fifun ohun ogbin lagbara atidena akolukogba se pon dandan fun ohun ogbin Bt bi o se pon dandan fun awon ohun ogbin miran ti a ko gbin lona biotech.

**KOKO KEWA. Agbekale ojo iwaju.** Ki a maa nireti pe ojo ola yoo dara pelu awon ere ti a n ri lodun nipase itewogba ti o to ida aadorun ninu ogoorun tabi ju beelo fun awon ti o se Pataki lara ohun ogbin imo-ero **biotech** t'o fi aye perete fun awon ohun ogbin to wa loja, ni awon orileede ti o sese ndagba ati onileese nlanla. Gbogbo olonajona lo ti kun fun awon ohun ogbin\ire oko biotech tuntun(eyi ti a gbodo gba ase ki a to gbin tabi raa wale) ti yoo wa fun teru-tomo ni nkan bii odun marun-un sibi ti a wa yii- a ni akosile awon ire oko ti o ju aadorin lo ninu ekunrere ojulowo akosile yii. Laraa won ni, awon ohun ogbin tuntun ati ire oko gbogbo atakokoro-tarun danu tii kii sigbe oro oogun apako yewo; a si ngbin Iresi goolu nipa fifi danle wo ati anamo ti kokoro kii baje ti a fi n danle wo ni Bangladesh, Indonesia ati orileede India. Ni orileede US, Simplot ti beere fun ase lati tubo safikun agbara idena arun ti anamo ibile ni ati lati din suga re ku; ki o le koju irufe awon ohun ogbin miran ti ko dara, papajolu ni Afrika, bi iru ogede ti a ti ree ati ewa ti kokoro ko lee da laamu; eyii mu ki o dabi pe ireti si wa; ibasepo\idokowo to wa laarin awon arralu ati aladani(PPP) ti n seso rere nipa pinpin ati siseto idagbasoke awon ire oko ti a ti fontelu- merin irufe awon ti a ti gbidanwo bee lo wa, leyii t'o n safihan oniruuru awon ohun ogbin ni awon orileede meta ni gusu ni a sagbeyewo re ninu ekunrere akosile yii. Ajo ti ko duro de ere, ti awon araalu ati awon aladani n fowo ran lowo ni ISAAA je. Eekan pere ni a ka gbogbo awon saare oko ti a fi sogbin imo-ero(biotech) ti a ko sile ninu awon iwe ISAAA, laifi ti iye adamo/akanse ti awon ohun ogbin naa ni se. Ekunrere alaye wa ni ISAAA Brief 49**"Ipo Ti Awon Ohun Ogbin Imo-Ero Ti O Wa Fun Tita Wa Lagbaye: Ti Odun 2014,** ti Clive James ko. Fun ibeere e wo ori ero ayelujara ti http://www.isaaa.org tabi ISAAA AfriCenter pelu +254204223618 tabi africenter@isaaa.org .